**Lakaye Ọrọ**

OLUKULUKU ohun ni akoko wa fun, ati igba fun iṣẹ gbogbo labẹ ọrun. Igba bibini ati igba iku. Iran kan nlọ, iran kan mbọ ṣugbon aiye duro titi lai.

# Irohin Yoruba

No. 801 OCTOBER 12 — OCTOBER 18, 1960 Kobo Meji (2D.)




Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# ỌMỌ-ỌBA ALEXANDRA GBA IYI NI IPINLẸ IWỌ-ORUN NAIJIRIA

## Awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe ariya fun Gomina atijọ



Aworan yi ni ti igbati awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe ẹyẹ fun Ọlọla John Rankine, Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun atijọ ati aya rẹ ti nwọn ti ilu wọn wa fun ajọyọ Ominira Apapọ Naijiria. Ninu aṣeyẹ ti awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe fun Gomina atijọ yi ati aya rẹ ni nwọn gbe ti fun wọn ni ẹwu aṣọ-oke, fila ati aropalẹ pẹlu iborun ati gele ati buba Nailonu. Inu wọn si dun si ẹyẹ yi, nwọn dupẹ pupọ, nwọn si gbadura fun ilọsiwaju Ijọba Ipinle Iwọ-Orun ati alekun idẹra fun gbogbo awọn enia Ipinlẹ Iwọ-Orun.



Aworan yi ni ti igbati Oloye S. L. Akintola, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Ọmọ-ọba Adeleke Adedoyin, Alaga Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nsin Ọmọ-ọba Alexandra wọ inu Ile Igbimọ Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria. Wọ irohin ati awọn aworan yoku loju ewe kẹrindinlogun.

## AKIYESI PATAKI

A fi iwe yi kesi ẹnyin Aṣoju wa ati ẹnyin onibara wa nibikibi ti ẹ ba wa pe ẹnikẹni ti ko ba ri Iwe Irohin ti o jade ni 28:9:60 ati ti 5: 10: 60 gba, ki o kọwe bere lọwọ Olotu, a o si fi ṣọwọ si nyin. Oju ewe mejilelọgbọn ni ọkọọkan awọn Iwe mejeji na ni, nwọn si kun fun oriṣiriṣi irohin, itan ati iwasu awọn oniṣẹ Ọlọrun ati oriṣiriṣi irohin Ajọyọ Ominira Naijiria.

Irohin ko to afojuba ni, bi o ba ra mejeji tan wa a tun gbiyanju ra fun ọrẹ rẹ. Nwọn gbadun pọ.

—OLOTU.

# Awọn mọkanla di Ọga Agba ile iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

LATI Ibadan ni irohin tere nla ti kan wa pe lati isisiyi lọ awọn ọmọ Naijiria ni yio ma a ṣe akọwe agba ni gbogbo ile iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, eyiti o jẹ pe awọn aṣeji ni nwọn ṣe e ri.

Oloye S. O. Adebọ ti i ṣe olori gbogbo awọn akọwe-agba ile iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti on paapa si jẹ Akọwe-agba ni ile iṣẹ eto owo ti Ipinlẹ na sọ ni Ibadan ni ọjọ 'Ru ti i ṣe ọjọ karun oṣu yi pe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Oloye S. L. Akintọla ti yan awọn ọmọ Naijiria mọkanla si aye akọwe-agba ni ile iṣẹ Ijọba Ipinlẹ na.

Awọn ti nwọn yan na ni wọnyi:—

Ọgbẹni T. O. Ejiwunmi, Akọwe-agba ile iṣẹ Ijọba ti ngmu ojuto eto ilera ati anfani ilu.

Ọgbẹni D. A. R. Alexander, akọwe-agba ile iṣẹ eto idajọ ododo.

Ọgbẹni C. O. Taiwo, akọwe-agba ile iṣẹ eto agbẹ ati awọn ohun iṣura ilẹ.

Ọgbẹni J. E. Imoukhuede akọwe-agba ile iṣẹ eto ẹkọ. Ọgbẹni J. O. I. Longe, akọwe-agba ile iṣẹ eto owo ati iṣẹ ọwọ.

Ọgbẹni J. M. Beckley, akọwe-agba ile iṣẹ eto Ijọba Ibilẹ ati ti awọn Ijoye.

Ọgbẹni F. T. Odunmeru, akọwe-agba ile iṣẹ eto iṣẹ ati ile owo Ijọba.

Ọgbẹni H. A. Ejueyitchie akọwe-agba ile iṣẹ eto owo. Ọgbẹni A. J. Wilson, akọwe-agba ile iṣẹ eto ile kiko ati ilẹ wiwọn.

Ọgbẹni N. O. A. Akinyẹmi, akọwe-agba ile iṣẹ eto iṣẹ ati igbokegbodo ọkọ; Ọgbẹni O. Batẹyẹ, akọwe agba ile iṣẹ eto aria ilu, ati ti ile iṣẹ eto irohin Ijọba ati ti agbademeji aala Ipinlẹ Iwọ-Orun.



Aworan yi ni ti igbati Oloye Adebọ wa ni ilu New York ni Amẹrika ti o si mba awọn Alakoso Ile-iṣẹ Eto Koko da'mọran nipa owo ati iṣẹ miran.

* * * *

Ninu awọn akọwe-agba tuntun yi, awọn mẹrin ni Ijọba yio ma yẹwo na. Awọn na ni Ọgbẹni Ejueyitechie, Wilson, Akinyẹmi ati Batẹyẹ.

Ijọba si tun ṣe ikede pe laipẹ yi, awọn yio yan ọga ile iṣẹ tuntun miran si ibi ti kol ti i si ọga.

Oloye Adebọ sọ ninu ikede rẹ pe yiyan ti Ijọba yan awọn ọmọ Naijiria si ipo nla yi, eyiti awọn Oyinbo ti wa tẹlẹ ri fi han gbangba bi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti ni itara si lati ri i pe awọn ọmọ Naijiria ti nwọn ba tọ si aye yi nipa ẹkọ ati mimọ wọn, bọ si aye wọnyi.

O ni ero lati yan awọn ọmọ Naijiria yi bẹrẹ nigbati Ijọba ti ṣe ipinnu pe ki awọn ọmọ Naijiria ti o ni ẹkọ ti ma a kọṣẹ labẹ awọn Oyinbo ọga wọn ki awọn na ba le bọ si aye wọn.

Nibi ase apejẹ t iOloye A.

Nibi ase apejẹ ti Oloye A mojuto irohin ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe fun awọn oniwe irohin Naijiria ati ilu okere, Oloye Adebọ sọ pe "kikọ ni mimọ", o si tun sọ pe pẹlu ogo Oluwa ati isowọpọ awọn alabaṣiṣẹ on, gbogbo oke iṣoro awọn nṣiaiyi yio di ilẹ, yio si rọ awọn lọrun.

Nibi ase na ni Oloye Akin Dẹkọ, Minista Alamojuto eto agbẹ ati ohun iṣura ilẹ sọ pe inu on dun lati ri i pe ati Oyinbo ati Enia-dudu nṣiṣẹ pọ lati mu eto ati iṣẹ Ijọba yọri si daradara.

## Adajọ sọ onisango ajọmọ gbe si ẹwọn ọdun mẹrinla

### Adajọ na ni o ṣe on laanu pe sẹriya na ko pọ to

OGBENI John Bennett, Adajọ-agba Kotu Asaisi l'Eko sọ baba onisango kan, Oyerogba Ajamu, ẹni ọdun mẹrindinlogbọn ti o nrin kaakiri laisiṣẹ pataki kan, sẹwọn ọdun mẹrinla oniṣẹ aṣekara ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ karun oṣu yi nitori pe o jẹbi ẹjọ ajọmọgbe ti awọn ọlọpa ba a ṣe.

Ọmọ ti awọn ọlọpa fi ẹsun ẹkunrin na sun pe o fiigbe ni ọmọ ọdun mẹfa kan ti nlọ si ile-iwe. Oruko rẹ si nje Ajọkẹ Ketose.

Awọn ọlọpa sọ fun Adajọ na pe, nigbati awọn ri ọdaran yi bi o ti ṣe ngmu Ajọkẹ Ketose lọ ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu kẹfa ọdun yi ni awọn ba fura si i pe o ji ọmọ na gbe ni.

Awọn ọlọpa ni nigbati awọn si bi i lere pe kini ba on pẹlu ọmọ na pọ, nṣe ni o nsọ kanun-kanun, gbogbo ohun t'o si nsọ ko ye awọn rara, o bẹrẹsi gbọn pẹpẹ, ni awọn ba mu u.

Ẹjọ ti ọdaran na ro ni pe on ko ji ọmọ na gbe rara. Nigbati on ṣe akiyesi pe, ọmọ na ko mọ ọna ile rẹ ni on ba fi ngmu u lọ si ọdọ iya rẹ, o ni ọlọpa si wa mu oni laiṣẹ. Ninu idajọ rẹ, Adajọ-agba sọ pe on ni igbagbọ si ẹsun ti awọn ọlọpa ka si ọdaran na lọrun, ati pe irọ nla ni ọdaran na pa lati sọ pe on ngmu ọmọ na lọ si ọdọ iya rẹ ni. O ni o ji ọmọ na gbe

Wo oju ewe kẹdogun

Kọ gbogbo awọn adamọdi silẹ !
Ojulowo kanṣoṣo
MENTHOLATUM
ni o wa
Ninu awọn idẹ ati agolo bawọnyi ni a nta wọn


FI OJU WA AMI-IṢOWO
MENTHOLATUM
IPARA TI O DARA JU GBOGBO IPARA LỌ

# ẸGBẸ ONI'ROHIN GBA ẸBUN IFE OMINIRA NLA

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ karun oṣu yi awọn ọmọ Ẹgbẹ Oniwe-irohin ti Naijiria gba ẹbun ife silifa (silver) nla kan lati ọwọ Ọgbẹni Claude Barnett, Alakoso awọn Ẹgbẹ Atẹwe ti Naijiria nibi ipade ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Oniwe Irohin na ṣe ni Eko. Ọgbẹni Barnett ati aya rẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ẹbun yi fun iranti ominira ti Naijiria.

Ki o to gbe ẹbun na le wọn lọwọ, Ọgbẹni Barnett sọ pe inu on dun lati wa pẹlu awọn Ẹgbẹ na. O ni eyi ki i ṣe akọkọ pade on pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ na, o ni ninu ọdun 1958 ni on kọkọ ba awọn ọmọ ẹgbẹ na pade inu on si dun pe nwọn mu gbogbo ero wọn ṣẹ nipa ile ipade ti nwọn kọ.

O ni laisi aniani- awọn iwe irohin ti mbẹ l'Eko ati ni gbogbo ilu Naijiria ti ṣe, nwọn si nṣe iṣẹ ribiribi lọwọ-lọwọ bayi fun anfani ati ilọsiwaju ilu.

O ni gẹgẹbi ọkan ninu awọn enia-dudu ti ngbe ilu Amẹrika ti awọn si ni anfani a ti ma a lo mọ awọn enia-dudu to wa lati ilu miran, on paapa mọ pe ẹlẹ kanna wa ni ara awọn ati awọn enia-dudu miran wọnyi.

O ni tẹlẹ-tẹlẹ ri, ọna to jin si ra wọn ko fun awọn ni anfani ati ma a sunmọ ara awọn daradara to, ṣugbọn idina wọnyi ti kuro nibẹ.

Ni ipari ọrọ rẹ, o ni pẹlu inu didun ni on fi fun awọn ọmọ Ẹgbẹ Oniwe-irohin ni ife nla na.





*     *



Aworan oke patapata yi ni igbati awọn aṣiwaju Ẹgbẹ Oniwe-irohin ti Naijiria nyẹ ife ominira nla ti Ọgbẹni Claude Barnett ati aya rẹ fi ta wọn lọrẹ wo. Aworan oke yi ni ẹgbẹ otun ni ti igbati awọn ọmọ ẹgbẹ na nfi ife nla yi han ọkan ninu awọn ọrẹ ẹgbẹ na, Ọlọfa Adetokunbọ Ademọla, Adajọ-agba Apapọ Naijiria. Ọgbẹni Barnett ni o duro si ẹgbẹ otun ninu aworan yi. Aworan oke ọwọ osi ni ti igbati Ọgbẹni Claude Barnett ati aya rẹ pelu awọn aṣiwaju ẹgbẹ na nyẹ ife ominira na wo.

# Itan bi Ijọ Enia-dudu ti ṣe gba ominira

## Lati ọwọ Ẹni ọwọ julọ Primate E. A. Olude, olori Ijọ Enia-dudu

LATI bi oṣu mẹta sẹhin ni gbogbo ilu ti nrọ kẹkẹ fun ajọyọ ominira ti Naijiria gba ni ọjọ kini oṣu yi. Lati bi ọsẹ mẹrin sẹhin si ni gbogbo ohun ti a o ṣe fun ajọyọ ominira wa na ti nfi ara han. Ominira na ti de, a si ti gba a. Ki Ọlọrun jẹ ki o tu wa lara, ki a si le fi ifẹ Ọlọrun lo o.

Ṣugbọn ija ominira wa yi na kọ ni akọkọ ija. Ohun ayọ to si tẹ wa lọwọ yi mu ọpọlọpọ enia ranti ija ati akatakiti ti awọn aṣiwaju ati awọn oselu [illegible] ti nwọn si ti ṣe sẹhin fun ominira ti ilu, ti ṣọọṣi ati fun ilọsiwaju awọn enia dudu.

Ọkan pataki ninu ija fun ominira ti ṣọọṣi na ni eyiti awọn aṣiwaju wa ja ti a fi ni Ijọ ti awọn Enia-dudu ni ilu wa loni. Itan bi nwọn ti ṣe da Ijọ enia-dudu na silẹ gun pupọ, emi yio si sọ niba ṣoki.

### ỌDUN MỌKANDILỌGỌTA

Nwọn da Ijọ enia dudu yi silẹ ni ọjọ kẹtala oṣu kẹwa ọdun 1901, ni ọjọ kejilelogun oṣu kejila na ni nwọn si fi idi rẹ mulẹ l'Eko. Orukọ Ijọ na ni Ijọ Bethel. O di ọdun mọkandinlọgọta bayi.

Lati inu Ṣọọṣi St. Pauls Breadfruit l'Eko ni nwọn ti ya, nigbati ọtẹ kan dide larin Ijọ na. Ọtẹ na ni wipe awọn ọpọlọpọ enia ninu Ṣọọṣi Breadfruit fẹ ki Johnson wa ni alamojuto Ijọ na, ṣugbọn awọn alaṣẹ Ijọ C.M.S. ko gba bẹ ẹ. Nigbati awọn alaṣẹ Ijọ CMS ko gba bẹẹ ni awọn ti ko tẹ lọrun ba binu yapa kuro ninu Ijọ na. Lati igbana ni ija ominira ti bẹrẹ.

Awọn ti o si kuro ninu Ijọ na le ni ẹdẹgbẹta enia ti nwọn si da Ijọ tiwọn (African Churh Organisation) silẹ. Ero awọn enia wọnyi ki nwọn to da Ijọ a silẹ ni pe ki aye ki o le gba wọn lati ma a sin Ọlọrun



Ẹni-ọwọ julọ Primate E. A. Olulode

* * *

ni otitọ laisi labẹ ajaga alamojuto Ijọ ajeji mọ.

### OGUN NLA

Ninu idasilẹ Ijọ yi, t'ile t'ode ni awọn enia gbogun ti wọn Ọlọrun si fun wọn lagbara, ti nwọn fi ṣẹgun igboguntini yi, ti iṣẹ Ijọ na si fi ntan kalẹ lọ siwaju ati siwaju.

Nigbati o di ọdun 1907, ẹdeaiyede kan bẹ silẹ ti o da Ijọ na si meji. Ninu awọn ti o yapa kuro ni Ṣọọṣi Bethel ni o da Ijọ ti Salem ni Ebue-Mẹtta ati Ijọ Zayọni (Zion) Eko silẹ. Eyiti iba fi mu ki Ijọ African rẹhin, nṣe lo tubọ nlọ siwaju si i, ipinya yi mu ki onikaluku Ijọ yi ma a pẹka kakiri agbegbe ilu, ti o si tubọ fi nkun agbara Ṣọọṣi African.

Nigbati o di ọdun 1916, awọn Ijọ mejeji yi African Bethel Church ati African Salem Church ti ni to awọn irinwo ẹka (400 Churches) nigbana ni ologbe ọgbẹni Frederick E. Williams dide si ọran na lati ri i pe ki Ijọ mejeji yi papọ. Nwọn si papọ ninu ọdun 1922.

Lati igbana ni awọn Ijọ yi si ti tun npẹka si i kakiri awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun, awọn ilu Ipinlẹ-Ariwa ati awọn ilu Ipinlẹ Ila-Orun, nwọn si kọ Ole Ile-isin (ti iṣe ibujoko awọn Biṣọpu) meji, ekinni ni African Church Cathedral Bethel l'Eko eyiti nwọn ya si mimọ, ti nwọn si ṣi fun Ile-isin Ọlọrun ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kọkanla ọdun 1928.

Ekeji ni African Church Cathedral Calabar eyiti nwọn ya si mimọ ti nwọn si fun Ile-isin Ọlọrun ni ọjọ kinni oṣu kọkanla ọdun 1958. Bi awọn Ijọ yi ti ngbilẹ, ti nwọn nkọ ṣọọṣi kakiri bẹni nwọn tun nkọ ile-iwe pelu.

Ni ọdun 1903 ni Ijọ Africa fi idi mulẹ ni Ijẹbu, ni ọdun 1916 ni nwọn fi idi mulẹ ni Abẹokuta, bẹẹ bẹẹ lọ ni Ibadan, Ilesha, Ile-Ifẹ, Oshogbo, Ikirun, Ọwọ, Iḳẹrre ati bẹẹbẹẹ lọ ninu awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Ninu ọdun 1905 ni Ijọ Africa bẹrẹsi fi idi mulẹ ni Calabar, ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu kini ọdun 1914 ni nwọn kọ ṣọọṣi Buguma, ni ọdun 1917 ni nwọn kọ ṣọọṣi ti Uyọ, ti Ekun Ilu Eket ni ọjọ kẹwa oṣu kọkanla ọdun 1924 lati igbana ni nwọn ti npẹka kakiri awọn ilu Ipinlẹ.

(Wo oju ewe kẹjọ)






SIERA radio

CALLING NIGERIA

SIERA radio

CALLING NIGERIA



SIERA

ARE THE FINEST RADIOS IN NIGERIA

go and see the wonderful range at your stockist TODAY

JOHN HOLT

DISTRIBUTE AND SER[illegible]C THROUGHOUT NIGERIA

# A dupẹ Ominira ṣ'oju ẹmi

## Lati owọ Ẹrukobodo—Eko

OLOTU, ẹ gba mi laye ninu iwe "Irohin nyin lati fi ẹ to'kun mi ninu ki gbogbo awọn onkawe ọmọ ilẹ Yoruba nile loko ati ni ilu okere fun aabo ti Ọlọrun da bo wa ti a fi jẹ ọkan ninu ẹniti ajọyọ ominira ilẹ ibi awọn baba nla wa ṣ'oju ẹmi wa.

Adura mi fun t'ọmọde-t'agba nilẹ Naijiria ni wipe, ki Oluwa ko jẹki asiko ominira ilẹ wa yi jẹ asiko owo, asiko ọmọ ati asiko alafia; ki Oluwa ko fi ibukun akunwọsilẹ sinu ile olukuluku wa, ki ile ko r'oju ki abẹ ọdẹdẹ wa ko tutu, ki aboyun bi tibi-tire ki agan di ọlọmọ, ki onişẹ ọwọ ko ma a ri şe, ki onişowo ko ma a ta ata jere, ki ayipada si buburu k'o jinna si onişẹ ọba, ki igi oko ma a so eso rere, ki awakọ ma a gunlẹ si ebute alafia, ki arinna-ajo maşe rin pade iku ojiji.

Ọlọrun, iwọ ni Ọba awọn ọba; iwọ ni ọba ti o ngbe ori itẹ Rẹ wo gbogbo agbaiye, jọwọ, maşai jẹki awọn ti o şe Alakoso ilẹ wa le ni iberu Rẹ l'ọkan, ki O si jẹki nwọn le ma a fi ẹmi otitọ ati ẹmi ododo tọ ọkọ ilẹ Naijiria ti a şẹşẹ kosi ina rẹ yi de ebute alafia.

**IGBA MẸTA NI IGBA**

Nigbati emi Ẹrukobodo, nri wipe asiko a ti gba ominira ilẹ wa kusi dẹdẹ ara mi nlọ tikọ, şugbọn nigbati mo gboju s'oke ti mo wo oke titi, ti mo tun ranti ọrọ awọn baba nla wa ti nwọn ma nsọ wipe, "Igba mẹta ni igba", ara mi tun ya gaga, şugbọn, igba ku-owurọ, ku asan ati ku-alẹ ti awọn baba wa nsọ, o yatọ si igba ti emi Ẹrukobodo ranti ti Adan mi fi d'orikodo, ti o nfẹ wo işe ẹiyẹ.

Igba ti mo ranti ni igba kini, ti işe igba aiye awọn baba nla wa lasiko ti nwọn nda Ijọba ara wọn şe, ti nwọn si fi otitọ ati iwọnba lakaye ti Ọlọrun fun wọn lo aiye wọn pẹlu igbadun.

Igba keji ni igbati awọn Ijọba Gẹẹsi g'oke, wa ba wa nilẹ wa, ninu eyiti a ni ọlaju, ti ọlaju wa na g'oke agba, ti ọgbọn wa re iwaju de ipo ti a fi di ominira ara wa loni.

Igba kẹta ti emi Ẹrukobodo fẹ sọrọ le lori ni igba ti asia Ijọba ibilẹ wa nfẹ lẹlẹ kiri ilẹ Naijiria loni; Ki Oluwa ko jọwọ, ki o maşe tun da wa pada sẹhin mọ, iwaju rere ni ki ọpa ẹbiti wa o ma a re si.

**OTITỌ NI I GBE ORILẸ EDE NIYI**

Emi Ẹrukobodo, ri i wipe, ẹnyin Alakoso ilẹ wa ẹ ti fo 'soko, ẹ ti bẹ ijo lori na, ohun ti mo fẹ ki ẹ mọ ni wipe, bi onişango b anjo, ti ko ba tapa, abuku onibata kọ, abuku onişango ni o.

Gbogbo orilẹ ede lo nkan saara fun işẹ nla ti ẹ şe ni aşeyọri ati gbogbo ọmọ ilẹ Naijiria na pẹlu, nitoripe, lati ọjọ ti alaiye ti d'aiye ẹnikan ko ti i fi şe itan pa ninu ilẹ Naijiria yi ri wipe, iran kan ti gba iru ominira ti a wa ninu rẹ yi, bi Ọlọrun ba şe ohun rere, ẹ tọ ni ki a dupẹ, 'toripe, a ri wipe, ero ọkan nyin o ba ti Olodumare pade.

Ohun ti mo fẹ fi kun ọrọ mi na ni wipe, ẹnikan ki l'abẹ opo asia Ijọba na, ẹ lọ parapọ, ki ẹ şe otitọ ati ododo, gẹgẹbi ẹ ti mọ şe, otitọ ni o ngbe orilẹ ede niyi.



ẸRUKOBODO

★ ★ ★ ★

Işe ore tan, ko loşo ti i, ki işẹ ribiribi ti ẹ şe yi ki o le dara fun nyin ati fun gbogbo mẹkunnu t'o mbẹ

Ki ọrọ mi na o le jẹ asọye, emi Ẹrukobodo, tun nsọ fun ẹnyin Alakoso ilẹ wa nihin wipe, asiko to lati mu iwa ẹgan, iwa eebu, ati iwa imọ ara-ẹni nikan kuro, ẹ parapọ, ẹ şe ara nyin gẹgẹbi ọmọ-iya-ọwọ, ki ẹ fi inu kan, ọkan kan, ati ẹmi otitọ şe işẹ rere, nitoripe, irẹpọ ati if'ohun ş'ọkan nyin ni irugbin rere yio ti hu jade, eyiti yio si wa bẹ ẹ titi ti awọn arọmọdọmọ wa yio fi de wa ba ohun ti ẹ ba şe silẹ.

Adura mi si ẹnyin Alakoso ilẹ wa ni wipe:—"Iye ata ki iku mọ ata ninu". Oluwa ko ni pa ọgbọn ati lakaye ti ẹ fi gbe ẹ de ibiti ẹ gbẹ de yi rẹ mọ nyin ninu, ajinde ara yio ma jẹ nyin.

**JIJỌ L'OJỌ ON KỌ**

Ninu ọrọ mi yi ni emi Ẹrukobodo yio ti sọ ni asọye fun gbogbo awọn ti o nro o l'ọkan wipe:—Nigbati a kuro labẹ Ijọba Gẹẹsi, t'a di alakoso ara wa yi, njẹ iwa irẹjẹ kọ ni so ma a hu si ara wa gẹgẹbi awọn kan tişe nhuwa lasiko igbati Ijọba Gẹẹsi nşe Alakoso ilẹ wa, ti nwọn finn-fẹdọ fi aşẹ ibilẹ ilu kọọkan da awọn oba ilẹ wa lọla. Eyiti o jẹ wipe, bi awọn ti ọba ilu kọọkan ba yan si onidajọ, ba ko ara wọn jọ bi mẹta, tabi bi mẹrin si ori akete idajọ wọn tan, iwa irẹjẹ tabi iwa ojusaju ni nwọn ma nhu lori ẹjọ kejọ ti nwọn ba fi siwaju wọn, debo ti nwọn ma nfi iwa irẹjẹ na han ẹnikẹni nipa ọrọ ẹnu wọn ti nwọn ma nsọ ni gbangba ile ẹjọ fun akowe abẹ wọn wipe:—"Ṣebi, awa ni a ni ki o ko ọ, awa na ni a ni ki o parẹ".

(Wo oju ewe kẹwa)


## The White Brotherhood Lodge Friendly Society

Ẹgbẹ ifẹ ẹnikeji rẹ gẹgẹbi ara rẹ.



... December 1960 lori eto pataki fun ajọdun ogorin ọdun ti a da ẹgbẹ yi silẹ. Yio dun mọ ni ninu ti awọn eka ẹgbẹ yi ti fin Nigeria, Ghana, ... France ati Liberia ba le fi ... KỌWE SI:—AKỌWE AGBA, c/o 18, ARAOTI Street; Box 44; Yaba—Nigeria.





# Itan bi Ijọ enia dudu ti ṣe gba Ominira

[illegible]








AMAMA nfun ni ni agbara

[illegible]

# Ọmọ-ọba Alexandra ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria













[illegible]

# A DUPẸ OMINIRA Ș'OJU ẸMI

(Lati oju ewe keje)

eyiti o jẹ wipe, bi enia ko ba ni baba nigbejọ, tabi baba-ogun, ko si ohun ti oluwarẹ le ṣọ niwaju wọn ti o le jare?

Emi Erukobodo, nṣọ o fun awọn ẹniti o leeo iru iyẹn lọkan si ominira ti a gba yi wipe:—'Ibiọ lọjọ, ki iṣe bẹẹ rara ', nitoripe ọgbọn wa ti rewaju, a si ti ni imọ ijinlẹ tayọ ki iru iwa bẹ tun ṣelẹ l'orilẹ wa, mo fẹ ki ẹnikẹni fi s'ọkan wipe, ominira idẹra ati ti ifọkanbalẹ ni eyi yio jẹ fun t ọmọde-t'agba wa l'agbara Odumare.

**ADAṢE NI IHUN NI**

Ohun ti ominira tiwa yi yio fi jẹ ominira idẹra fun tọmọde tagba wa ninu ilẹ Naijiria ni wipe, a ko da a ṣe, bi o tiṣe jẹ ifẹ inu wa nilẹ wa nihin, bẹ ẹ na ni Ijọba ilẹ Gẹẹsi ṣe finnufẹdọ fi le wa lọwọ. Ki ntun ṣọ ọ ni asọye; oga ni Ijọba Gẹẹsi jẹ fun wa, a ti kọṣẹ labẹ wọn, a si ti yege, bi ọmọ iṣẹ ba yege labẹ ọga rẹ, ti o si di ominira ara rẹ, ẹ tọ ni ki ọmọ iṣẹ na tẹle ilana ofin ti ọga rẹ ba fi le e lọwọ.

Nitotọ ni a ti kuro ni abẹ opo asia Ijọba Gẹẹsi, ngbegbe, ofin ti nwọn ti fi kọ wa ko kuro lọdọ wa. Ki ẹ le mọ daju gbangba wipe, ofin Gẹẹsi ni a o ma a lo, ki a to gba ominira yi ni awọn Ijọba ilẹ Naijiria ati awọn Ijọba ilẹ Gẹẹsi ti pa imọ wọn pọ yan aṣoju si arin ara wọn; loni, Ijọba ilẹ Naijiria ni aṣoju tirẹ nilẹ wa nihin, eyi ni ko le mu wa yapa kuro ninu ofin ati iwa Gẹẹsi lailai.

**A KI I SIN ARA ẸNI K'A SUNKUN**

Ohun pataki ti Emi Erukobodo, nfẹ ki gbogbo awa ọmọ ilẹ Naijiria mọ lati oni lo ni wipe, "Bi nwọn ba sọ wipe, o di ọwọ Imale, Imale, a si ni o di ọwọ Ọlọrun'. Ohun ti o mu mi sọ eyi ni wipe, ẹnikẹni ti o ba ti wa ninu ipo ti Ọlọrun to wa si nilẹ Naijiria loni, oluwarẹ ni lati mọ ohun ti o nṣe, gẹgẹbi owe awọn baba nla wa to sọ wipe: "Awọlu ma tẹ, iwọn ara rẹ lomọ', kosi ohun ti nwọn npe ni Iwọn-ara bikoṣe wipe, ki olukuluku wa o koju mọ iṣẹ rẹ, yal' ni abẹ Ijọba, tabi ni abẹ onisowo, bi o tilẹ jẹ onisẹọwọ ni ọ, mura ki o ṣe iṣẹ rẹ ni a ṣe kara-kara gẹgẹbi o ti mọ pe, 'Ẹnikan ki i sin ara rẹ ko sunkun'.

Kosi ẹniti yio mọ iṣẹ rẹ ni iṣẹ, ti koni ri irọrun ninu ipo kipo t'o wu ko le wa ati wipe, iṣẹ aṣekara wa nikan ni o le ran wa lọwọ, ti awọn oṣelu ilẹ wa koni le raye fi oju iṣẹ wo wa, tabi ki nwọn ka wa kun alaimore.

Gbogbo ẹniti ki i ba ṣe ọlẹ, ole, tabi alafọwọfa, kio lọ fi ọkan balẹ, asiko rere ni eyi yio jẹ fun gbogbo wa; ile koni le wa, ọna koni na wa, Oluwa koni jẹki a ri ogun-adaja, ajinde ara yio ma a jẹ fun gbogbo wa."

Ọmọ-Olubuṣẹ ki hyin o, o digba kan na o.




# Omidan Ayọdele Thompson se ọjọ ibi rẹ

YABA

OMIDAN Ayọdele Thompson ṣe iranti ọjọ-ibi rẹ laipẹ yi. Ni ọjọ na ni o di ẹni ọdun mọkanlelogun. Ẹṣẹ awọn ẹbi, ọrẹ ati gbajumọ ni o pe si ile Omidan Thompson na ni 13, Akinwunmi Street, Yaba; nibẹ ni o gbe ti ṣe ajọyọ ọjọ ibi na.

Oṣi fi orişirişi onjẹ ati oti tẹ wọn lọrun. Orişirişi ilu ni o pe sibẹ, bi nwọn si ti njo ni nwọn njẹ ni nwọn si ngmu. Iya rẹ nawo pupọ, ajẹti ati amuti ni awọn alabaṣeyẹ ọjọ na fi jijẹ ati mimu ṣe. Irohin ko to afojuba ni aṣeyẹ ọjọ na, o dun o larinrin.

Ki Oluwa jeki Omidan Thompson ṣe ọpọlọpọ ọdun ti yio ṣe e ni anfani laiye o.

**Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"**



# Ọmọ Naijiria di alakoso iṣẹ Shẹlli ni Apapa

OGBENI E. O. Ogundipẹ ni yio ṣe akoso gẹgẹbi Oga-Alamojuto Ile-iṣẹ Shell ni Apapa lati ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun yi titi di ipari oṣu kini ọdun 1961 ti Ogbẹni H. Wijmer Oga-Alamojuto Iṣẹ pataki yio pada de lati ilu Oyinbo. Iro daradara yi wa lati ẹdọ awọn alakoso Ẹgbẹ elepo ti njẹ "Shell Company of Nigeria, Limited".

Ẹni ọdun mejilelogbọn ni Ogbẹni Ogundipẹ, ni Ile-ẹkọ Giga Baptist Academy l'Eko ni o ti jade ẹkọ. O wọ ile iṣẹ Shell gẹgẹbi oṣiṣẹ-atẹwe 'typist' ninu ọdun 1946. O ti ṣiṣẹ larin awọn oṣiṣẹ Shell ni Ghana ati Saro (Sierra Leone) ati ni Naijiria pẹlu, o si ti kọ ẹkọ-giga ni ilu Oyinbo. O ti gbeyawo, ọmọ mẹrin ni Ọlọrun si ti fi ta a lọrẹ.

Ile-iṣẹ ogidi-epo kanṣoṣo ti o wa ni Naijidia ti o jẹ-wipe lati rẹ ni nwọn fẹrẹ na okowo adọta-ọkẹ pọnun (£1,000,000) tan si, wa ninu awọn ile-iṣẹ ti yio ṣe amojuto rẹ. Inu rẹ gba ọkẹ-meji le lẹgbaajọ tọnun epo (56,000 tons) on si ni ibudo-epo fun ọgọrin tanki wangonu Reluwe ati ogoji mọto-akepo nlanla.

Ni Apapa, Ọgbẹni Ogundipẹ ni yio ma a ṣe akoso igbokegbodo iṣẹ awọn ọrinlugba o din marun (275) awọn oṣiṣẹ ati iṣẹ pipin epo-mọto yika gbogbo Apapọ Naijiria ni gbogbo ọna mọto, ni ọna Reluwe ati ni oju-omi.

Larin asiko ti o ba wa ni Naijiria yio wa ni abẹ akoso ọmọ Naijiria.

## ITUMỌ ALA

### Lati owo Josefu Alala

ṢỌỌṢI—Ti o ba ri Ṣọọṣi loju ala yala nwọn nkọrin ni o, tabi ti enia ko si ninu rẹ ni, ala rere ni; maṣe bẹru ohun rere ti o rope ko ni to o lọwọ lasiko yio bọ si ni aipe.

EEBU—Ti o ba lala pe nwọn nbu ọ ni oju ala tabi iwọ paapa ni o nbu enia igbega ni itumọ ala yi, ṣugbọn ṣọra gidigidi lọwọ awọn ọdalẹ ọrẹ.

OFURUFU—Ti o ba ri ofurufu tabi awọsanmọ loju ala, iwọ ko ni pẹ gbọ iro rere lati ọna jinjin wa.

SALỌ—Ti o ba lala pe o sa mọ olopa lọwọ tabi o ri ẹniti o sa mọ olopa lọwọ ikilọ ni itumọ ala yi; ti o ba fẹ huwa aimọ kan ṣọra lasiko na.

IDALE—Ti o ba lala pe o lo si idalẹ tabi o nti idalẹ bọ, ṣọra ki o ma ba a padanu ninu ohun ti o ba dawọle lasiko na.

OPỌ—Ti o ba lala pe o ri ọpọ nkan bi owo tabi nkan ini loju ala ṣọra gidigidi ki o ma ba a padanu ti o pọ lasiko yi.

#### AKIYESI

A ko gba ẹnikẹni laye lati bere ju ẹyọ ala kan lẹẹkan. ẹnikẹni ti o ba lodi si imọran yi itumọ ala rẹ ko ni jade ninu "Irohin Yoruba", ekeji ẹwẹ, ẹnikẹni ti ko ba ko ibere itumọ ala rẹ ki o han rekete, ko ni jade bakanna ninu "Irohin Yoruba".

Ko si itumọ ala ti ẹniti ko ni jade ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti oluwarẹ ba ti posu Ibere Ala rẹ ṣowo si wa. E ma a ra Iwe "Irohin Yoruba" lọsọsẹ fun Itumọ Ala ati Itumọ Ala awọn Onibere.

JOSEPH ALALA, Mushin


## ORIKI BAMWO



Bamwo de, alajela ọmode, agbomola bi oriṣa. Akọkọluko ogun ti nda'molekun igbona, alaia ogun ti np'otutu fẹ warawara. O s'abiku d'ikugbagbe, o ṣ'ọmọ ti nh'ehin lore. Iko ri i sa. Iba ko o l'ona ta giri. Aipeẹi ri i d'ẹkun iyonu. Olugbala f'ọmọ si nyagbe orin. O k'apa inuwọ, o lu jedijedi l'alupa; gbogbo abiyamọ nyọ ṣeṣe. Ela ri i, o ro'ju. Orere ri i o na 'gbe bora. Eyi npa'lẹmọ lodilẹsọ. Ore ikoko, Kosemani awọn abiyamọ, eni araiye nijiadu ra. Wa ra a lodọ wa: Igo kekere 2s. 6d., Igo nla 4s. 6d. Owo-ọkọ 1s. 6d. Kowe si wa fun arapọ lati gba ẹdinwo.

**The Egba Trading Aradan Stores**

144, Denton Street, 18, Denton Bridge St., P.O. Box 2, Ebute-Metta. 46, Victoria Street, Lagos ati New Motor Park, Ibadan.



## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

OGUN Isoye 5s. post owo si MANAGER, Box 73, Ilesha.

**AKIYESI**

6th, 7th, 8th & 9th Books of Moses lede Yoruba £1. pere. A le ri ra ni 15, Araoti Street Yaba, Nigeria.

**MO JUBA AIYE**

FUN ohun elo to jẹ mọ Iṣẹ Ogboni ati ohun anfani miran. Fi stamp oni toro (3d. stamp) fun iwe Aiye Akamara. APENA, 75, Haastrup Street, Surulere—Nigeria.






**O ṣeṣe de si ile-itaja adugbo rẹ ni !**

Ajapa Alawọ-Aliga ni ẹni ayanfẹ ti o le ri lara gbogbo awọn Panu-onjẹ ti Ile-Iṣẹ Alumaco titun ṣe ni Apapa. On ni o joko lori awọn ikoko-irin-afuyẹ ati awọn panu ti o ndan yanranyanran ti o si nwoye pẹlu ifaiyabalẹ si ara rẹ nibẹ yi. O le jẹwipe bi o ti wi ni o ri—awọn ikoko ati panu rẹ ni o darajulọ ti o le ra—wọn lagbara tọ bẹ ẹ gẹ ẹ, nwọn ko le faya tabi ki nwọn dipẹta. Nwọn tun dinwo pẹlu nitoripe nwọn ni alopẹ pupọ ju iru awọn awo-onjẹ miran lọ. Ma a fi oju wa Ajapa Alawọ-Aliga ni Ile-Itaja adugbo rẹ.

AWỌN AJAPA ALAWỌ-ALIGA jẹ ayanfẹ pataki ninu gbogbo awọn Ile-idana igba isisiyi.

ẸNYIN ONIṢOWO
Bi ẹ ko ba ti i ra awọn Ajapa Alawọ-Aliga sinu ṣọbu nyin—ẹ tete wa ri wa kiakia.

Awọn ti o nṣe nkan ni

**ALUMACO, P.O. Box 60, Apapa, Lagos.**

Telephone: — 55715

# Ija Ọbaro Kabba d'opin

**" Idile mẹta l'ọba tọsi ni Kabba . . . . . . lati igba lailai ni awọn adugbo mẹfa-Kabba, Katu ati Odolu ti wa ni agbegbe owe . . . . ."**

*[ Lati ọwọ Micheal B. Aṣaju, Aṣoju Iwe Irohin Yoruba ]*



M. B. AṢAJU

NINU Iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ yi, Michael Aṣaju pari itan rẹ ti o ti nkọ lati ọsẹ kẹta sẹhin nipa ijadu oye Ọbaro Kabba. Ipari itan na bẹrẹ bayi:—

Lẹhin eyi ni Oloye Aka wa fi ẹnu kan ọrọ eto idile oye ọba ni Kabba. O ni idile mẹfa ni o njẹ oye ọba ni Kabba, awọn idile mẹfa na ni:—Ilemuna; Idọgba; Ilajọ; Ugbo; Ọdọgba ati Okere o si tun ṣe alaye ṣiwaju pe, ẹnikẹni ninu awọn idile wọnyi ni o ni ẹtọ lati jẹ oye Ọbaro tabi oye Ọdọfin ati oye Ọbayẹmi.

Oloye Aka tun sọ wipe, idile Idogba ni on ti wa tẹlẹri ati wipe o to Ọbaro mẹjọ ti o ti joye ni idile on, o ni nigbati Ijọba Gẹẹsi de ilẹ Kabba, Oloye Ọbaro Ogbaiyero ni nwọn ba lori oye, nwọn si ṣe eto pe ki nwọn ma a jẹ oye Ọbaro ni idile Ilajọ. Nipa agbara eto titun yi ni Oloye Ọbaro mẹjọ fi jẹ tẹle ara wọn ni idile Ilajọ.

**ADUGBO MẸTA**

Oleye Aka si pitan pe, lati igba lailai ni awọn adugbo mẹta, Kabba, Katu ati Odolu ti wa ninu agbegbe Owe, Kabba. O ni ki on to jẹ oye Ọbaro ni on ti ni iyawo marun, ọmọkunrin mẹjọ ati awọn ọmọbirin mẹtala. Nipa ti ariyanjiyan ti o wa nilẹ nipa wipe, boya, Oloye Aka yio lọ sile oye kan tabi Afin ọba kan ti o jinna to idamẹta ibusọ si ile ti on funra ara rẹ kọ, o ni on ko ni kuro ninu ile on niwọn igbati awọn enia Kabba ko kọ ile oye kan sọtọ yatọ si eyiti nwọn ti kọ silẹ fun ọba.

Oloye Aka tun sọ siwaju pe, on nilati ri i wipe, Ijọba Ibilẹ Kabba (Owe) kọ "Ile-ajẹwọ" kan ti ẹnikẹni ti o ba jẹ oye yio ma a lọ gbe ibẹ, o ni idile Ilajọ ni o kọ eyiti gbogbo enia mọ ni Afin titi di isisiyi. Ninu eto ifinijoye ti Oloye Aka ṣe, o ni nipa ilana eto gẹgẹbi aṣa ibilẹ ilu Owe Kabba, on nilati gba ibukun lọwọ awọn olori adugbo mẹtẹta, Odolu, Katu ati Kabba.

Oloye Aka ni, ẹniti ko ba ti i de ipo Ọrọta, ko le jẹ oye Ọbaro, nitori idi eyi, gẹgẹbi eto ifinijoye, Ọbaro ni, nwọn nilati ṣe etutu Arawo ninu ẹto etutu yi ni nwọn si nilati fa ori fun ọba titun na. Odidi ọjọ meji ni yio fi wa ninu ile rẹ ti ko si gbọdọ jade sode, eyi ni a npe ni 'Iyawo-oye' Ni ọjọ keje yio lọ si oko, eyi ni a npe ni "Iwọko". Eyi si jẹ iranti lati fi sọ fun Ọba na pe "Ninu Iṣẹ-oko ni a bi Iwọ ọba si". Eyi ni abayọri ọrọ ipade temi pẹlu Ọbaro titun. Ade a pẹ lori, bata a pẹ lẹsẹ, oye a mọri o.



Aworan yi ni ti igbati Ọba Daniel Aka, Ọbaro titun, wa ni ẹnu iṣẹ Ijọba ki o to jọba. Ọgbẹni Olabayọ ẹniti mba a du oye na ni o wa ni ẹgbẹ otun ninu aworan na.




## Ni orukọ Allah, Olore-ọfẹ, Alaanu-julọ

# Ẹ ku amojuba Ominira

## Lati owọ Mohammed Ameen

"NIGBAYI ni awọn alaigbagbọ to sọ ireti ati se ipalara fun ẹsin yin nu. Nitorina ẹ ma se beru wọn mọ, kaka bẹ ẹ Emi (Ọlọrun) ni ki ẹ ma a beru. Lati oni lọ ti Mo ti sọ ẹsin yin di pipe perepere fun yin ti Mo si ti pari oju rere Mi le yin lori nigbati Emi (Ọlọrun yan Islam fun yin gẹgẹbi ẹsin."—Alkurani Mimọ 5: 3.

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni aṣẹ tẹ Naijiria yi iṣẹ, gẹgẹbi eto, pe ko tan si iberu mọ fun wa, nitoripe a ti mu ori bọ kuro l'abẹ ẹru, akoso ijọba ilu wa ti bọ si ọwọ wa. Ọjọ na ni o dabi enipe Ọlọrun, nipa anu Rẹ, ti pari oju rere Rẹ le wa lori, eyiti o se ilu wa yi ni di ntilo ede ti o pe perepere nigbati aṣẹ ominira, lati se alakoso ara ẹni, ti tẹ awọn alaṣẹ wa lọwọ. A ko ri ohun fun ayọ ayafi ki a dupẹ fun Oluwa pelu gbolohun pe: "Gbogbo ẹyin ti Allah ni, Ọba gbogbo agbaiye!"

### ỌRỌ ỌLỌRUN

Eleyi lo mu wa ranti pe, ni nkan bi ẹgbeje ọdun sẹhin ni sọkalẹ ọrọ Ọlọrun de wa ba Anabi Ọlọrun loke Arafat ninu Hadj Ojiṣẹ Nla ṣe gbẹhin nigbati Ọba Adẹda ni ki Anabi Ọlọrun so fun awọn Musulumi pe ki nwọn f'ọkan wọn balẹ, ko si ifoya pe boya awọn Kafiri le pa ẹsin wọn lara mọ. Nitoripe awọn Kafiri ti sọ ireti lati ṣe ipalara fun ẹsin Islam mọ.

Ohun ti o yẹ ki a wa bi ara wa lere nipe: 'Loto a ti gbaṣẹ ominira dani na, bawo li a ti ma a gbagbe ti ominira na ko fi ni yi biri di Omi-inira mọ wa lọwọ lojiji? Ọlọrun ko ṣ'owa ndbẹ. Amin.

Ni'bayi ni gbogbo awa Musulumi ni lati mọ pe a ni iṣẹ palaki lati ṣe nipa iwa ati iṣe wa si Ọlọrun Ẹlẹda wa ati si awọn ẹda ẹgbẹ wa yoku. Ṣugbọn ki a le mọ riri awọn iṣẹ ribiribi na, o yẹ ki a kọkọ mọ ki li nkan na ti a npe ni Islam, nitoripe ẹlomiran kan njẹ Musulumi ni, ko mọ nkan ti o njẹ ẹsin Islam.

### ẸSIN ALAFIA

Idi niyi ti o fi yẹ ki a mọ kini Islam duro le l'ori ati bawo ni a le gbe ọran ẹsin na gba ti ako ni fi padanu rẹ? Lona kini, Islam ni ẹsin alafia ti o si fi ifẹ ati ifẹ ara ẹni silẹ fun ifẹ ti Ọba Ọlọrun nikan, eyiti o duro lori opo marun. Awọn ti nwọn gba Islam gbọ gẹgẹbi ẹsin ni a npe ni Musulumi.

Opo kini ninu Islam ni: Ijẹri pe ko si ẹni na ti o yẹ lati ma jọsin fun ayafi Ọba Allah, atipe Mohammed ṣe Ojiṣẹ Allah. Ijẹri yi li ede Larubawa ni a npe ni Kalimat Sahadat. Idi ati itumọ eleyi ni pe ko si Ọba bi Allah, ẹniti o jẹ ọkanṣoṣo. Iai ko ni alabapin tabi orogun, a ma njẹri yi nigbogbo igba paapa ninu awọn irun wa lẹhin ti a ba ti wọ inu Islam tan.

Iha kan ninu ijẹri yi nipe bi a ba mọ ipo Ẹlẹda wa dajudaju, ko si ohun ti o le ṣi wa lọna. Eyi yio si jẹki a mọ ẹtọ wa si ilu wa.

### RIRI OMINIRA

Ẹniti o ba mọ kini Islam jẹ ti o si ntẹle ẹkọ rẹ, yio mọ riri ominira ti a gba yi. Ẹniti o ba jẹ Musulumi ododo yio mọ wipe ominira ko fun ẹnikankan ni aṣẹ tabi anfani lati ṣe nkan-bi nkan ti o ba wu oluwarẹ ni buburu.

Islam nkọ wa pe ki a tẹ pa mọ iṣẹ wa, ki a sin Oluwa wa lọna ododo ki a ma hu iwa buburu, ki a jinna si nkan ti ko dara, ki a ma a ṣe daradara nigbakugba, nibikibi ati ni ọnakọna.

Ẹsin Islam pe perepere. O si mọ Islam ko fẹ iwa ẹgan, iwa-jamba, iwa igberaga; ohun ti Islam korira ni idọti, iwa aibikita, iwa aifi-eni-peni, iwa aini iteriba si ẹniti o ju wa lọ, ati iwa bitibiti.

### TANI MUSULUMI?

Enia ki i jẹ Musulumi ki o tun fi nkan miran wé Ọlọrun. Musulumi ododo ẹniti o nfẹ ran ọmọ ẹnikeji rẹ, ẹniti o nṣe iranlọwọ fun alaini ẹniti o ni iwa irẹlẹ, ẹniti o si nwa alafia ati ifi aiya-balẹ ile rẹ ilu rẹ ati gbogbo awọn ti o rọ kiri ka a.



MOHAMMED AMEEN

Ki a to da gbere pe itẹsiwaju di ọjọ mejọ (bi Ẹlẹmi ko ba gba a )pẹlu awọn opo ẹsin Islam yoku, ohun ti o yẹ ki a fi si iranti ju nipe: Islam ni ẹsin alafia, Musulumi si ni ẹniti o wọ inu ẹsin Islam lati le ba a ju ara rẹ silẹ ati lati le tẹriba fun awọn ifẹ, ofin, ati ilana Ọba Allah, atipe ẹnikẹni ti o ba ti ju ara rẹ silẹ fun oju rere ti Ọba Allah pẹlu iwa rere, ere iṣẹ rẹ mbẹ lọdọ oluwarẹ, iberu ko tun si fun oluwarẹ bẹni ọran ibanujẹ ko ni ba a.

Ẹ ku afojuba ominira. Oluwa ko ṣe e ni orisun ibukun ati ikẹ on igẹ Ọlọrun Ọba fun gbogbo wa. Amin.




## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọ ọ sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹ ẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU

# ỌMỌ-ỌBA ALEXANDRA GBA IYI NI IPINLẸ IWỌ-ORUN NAIJIRIA

LATI igbati Ọmọ-ọba Alexandra, ti iṣe aṣoju Ọlọla-julọ Alaiyeluwa Elizabeth Keji Ọbabirin Gẹẹsi ninu ajọyọ Ominira Naijiria ti wọ Ipinlẹ Iwọ-Orun ni o ti ngba iyi ati ọyẹ.

Ọmọ-Ọba na fi ilu Eko silẹ ni dede agogo mejila ọsan ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi, o si gunlẹ si Ebute ọkọ ofurufu ni agogo mejila-abọ ọjọ kanna. Gbara ti Ọmọ-ọba na ti gunlẹ ni Ọlọla Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi Kini Ọni Ifẹ, ti iṣe Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ti lọ pade rẹ, Oloye S. L. Akintọla ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun si tẹle e, ati Ọba Ọwa Ilesha ti iṣe Alakoso Igbimọ awọn 'ọba-l'ọba Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Lẹhin ti Oloye Akintọla ti ki Ọmọ-Ọba na ku-abọ tan, o si fi Alaiyeluwa Ọwa Ilesha ati awọn Minista, Alaiyeluwa Biladu Keji, ati Oloye S. O. Adẹbọ ti iṣe Olori awọn Akọwe-Agba ile iṣe Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun han Ọmọ-ọba na. Bi o ti ṣe eleyi tan ni Ọmọ-ọba Alexandra ati Ọlọla Gomina wọ mọto ayọkẹlẹ lọ si Afin Gomina.

Lati igbana ni awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nṣe ariya fun Ọmọ-ọba na titi fi di irọle ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ti Ọmọ-ọba na fi kuro ni ilu Ibadan lọ si Ẹnugu ni Ipinlẹ Ila-Orun, lati ibẹ n'o si ti kọja si Ipinlẹ Ariwa ni ana (11-10-60).

* * *

Aworan ẹgbẹ yi ni ti igbati awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun nṣe ere idaraya fun Ọmọ-ọba Alexandra ni Ibadan. Oloye Iyaafin Faderera Akintọla (aya Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun) ti o nṣe alakoso ere aladun na ni o duro larin wọn yi. Aworan isalẹ yi ni ti igbati Oloye Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ngba iwe-ẹri (Certificate of Friends of Nigeria) lọwọ Ọgbẹni Stonington ti awọn Oyinbo kan ti o da Ẹgbẹ ilọ (Friends of Nigeria) silẹ fun Oloye Akintọla fun ikini-ku-orire ti Ominira Apapọ Naijiria yi.




## Da Ikọ Otutu Duro

Ti o ba nwukọ tabi o [illegible] ti o ko si le sun dada [illegible] lọ ra MENDACO [illegible] MENDACO [illegible] Lọ ra MENDACO loni [illegible]



## F'opin si irora Lakuregbe lati oju orun

[illegible] Ẹrẹ (Kidney) [illegible] CYSTEX [illegible] Ra CYSTEX [illegible]

**Cystex**

Fun awọn Ẹrẹ (Kidney) Lakuregbe, Ile-ilọ.




Published by Allied Newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" odun kan—Ṣile mẹjọ ati kobọ mẹfa (8/6d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun ṣile mẹtala (13/-). Olotu S. M. Adẹmuyiwa, 2 [illegible] Street, Odi-Olowo, Mushin.